TO LET

3, Large Rooms
2, Small Rooms
1, Parlour
With Modern Amenities at:-
**24, Oliyide Street, Odo-Abore Mushin**
c/o Phone 21985.
or 16, Bamgbose Street, Lagos.

IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

Wanted

TO BUY
VACANT LAND
ANY WHERE IN
LAGOS 200 X 200
PHONE 24318.

VOL. V No. 314 MONDAY JANUARY 29 — FEBUARY 4 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# IPADE NLA GBOGBOGBO TI AFIRIKA DUN PUPỌ

## Oba Ethiopia to se epe fun Mussolini fi enu re sure fun ile Naijiria. Itiju nla lo je fun awon ilu ti kole wa

EKO:- NI ỌJỌ ỌJỌBỌ (THURSDAY 25TH JAN.) ITAN NLA ṢẸLẸ NI ILU WA NAIJIRIA, GBOGBO AWỌN OLORI, OLOTU ATI ALAKOSO ILẸ AFIRIKA ATI MALAGASY BẸRẸ IPADE FUN ILỌSIWAJU ATI ISỌKAN AFIRIKA. KI O TO DIPE AWỌN OLORI OLOTU ATI ALAKOSO BẸRẸ IPADE NI AWỌN ALASẸ ETO OKERE JAKEJADO AFIRIKA TI KỌKỌ ṢE IPADE BI WỌN O TI ṢE IPALẸMỌ FUN WỌN.

Ni ọjọ ọjọru (Wednesday 24) ni awọn alejo wa na bẹrẹ si wọ'lu ti Gomina agba Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe Olotu Ijọba Apapọ, Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa ati Alaṣẹ Eto Okere fun Naijiria Ọgbẹni Jaja Wachuku nlọ ti wọn mbọ si Ibudo ọkọ Ofurufu ni Ikẹja. Ilu Mọkanlelogun lo pejọ sibi Ipade yi.

**OBA AWON OBA**

Ninu awọn alejo pataki wa ni Kiniun Juda Ọba awọn Ọba ẹniti o ṣepe fun Mussolomi Ọgagun Italia ni ogun ajakaiye keji ti won si fokun so lọrun pa ni Ilu rẹ nitori o yaju si Ọba yi ti gbogbo Aiye mọ bi Ayanfẹ Ọlọrun. Ọba na sure fun Naijiria Ire na a si mọ wa lori. Ọlọla Gomina Agba Dokita Azikiwe lọ si ipade na Ninu Ọrọ rẹ, si gbogbo awọn enia Afirika pe ọkanna ni gbogbo wa jẹ atipe a gbọdọ ni lati ṣe ọkan. Ọba Haile Selessie sọ wipe a gbọdọ ṣiṣẹ pọ ki orilẹ Ede Afirika tu bọ Lọla siwaju si i. Iṣẹgun ni fun wa Ọba Eledumare yio si gbe wa leke. Ọba sọrọ yi lorişirişi, bakanna ni Dokita Azikiwe.

Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Olotu Ijọba apapọ Naijiria ni o ṣe atukọ ikọ Naijiria lọ sibi ipade nla yi. Diẹ ninu awọn ilu ti o wa ni wọnyi pẹlu orukọ awọn alakoso tabi olotu wọn Liberia (Kurumọ) Ọlọla William Tubman Dahomey ọlọla Huba Marga Sieria Leone (Ṣaro) ọlọla Milton Margaa Senegal ọlọla Seelar Songhor Ivory Coast Ọlọla Houphuet Borgun Congo ọgbẹni Kasavubu Niger ọlọla Haumani Diori ati awọn ti aye ko kosi lati darukọ wọn.

Ipade na si nlọ lọwọlọwọ bayi, lori ohun ti wọn ti mu ẹnu le ni ominira fun gbogbo Afirika, iṣọkan Afirika idagbasoke owo ati aiye itura fun gbogbo ọmọ Afirika ati ohun ọpọlọpọ ti o le mu idẹra ba orilẹ ede Afirika. Ki Ọlọrun Ọba Eledumare jẹki ipade na yọri si rere o. Amin. Naijiria ẹku alejo o.



Aworan yi niti Ọba Haile Selassie, Kiniun Juda, nigbati Olotu Ijọba apapọ Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, nki K'abọ sibi Ipade awọn olori oṣelu orilẹ-ede Afirika ati Malagasy. Ọlọla T. O. S. Benson lo duro lẹhin Balewa.

# Ọrọ Olotu

## Alafia logun oro, Tete yara lo ko Nomba, nitoripe Ija-fara lewu

GBOGBO ẸNYIN Ọnkawe wa ni ẹ ti mọ pe iṣẹ wa ni lati ma tọ eni si ọna, gẹgẹbi orukọ wa, a ko gbọdọ ri ohun dudu ki a pe e ni funfun, tabi ki a ri ohun ti yio ṣe enia ni anfani ki a si sọ pe ko dara, nitorina ni a ṣe ti ọrọ Bupa-bupa ṣe ẹṣin ọrọ wa ọsọ yi.

Ki Oluwa maṣe na ọwọ arẹ si wa, Ọlorun Ọba jọwọ maṣe jẹki arun Ṣanpọnna di wa lẹnu Ijẹ. Amin. A pe gbogbo ẹnyin Ọnkawe wa asiko to lati ma lọ kọ Nọmba nitori arun Ṣanpọnna, nitori apa bubu yi ni ko ni le jẹki arun na kọlu wa ẹmi wa yi ko pe meji Ijafara si lewu pupọ nitorina abẹ ẹnyin ti ẹ ba ri pe ẹ koiti kọ lọdun ni, ki ẹ tete lọ kọ ti yin.

Oni yi li o pe ọsẹ kan ti Ijọba ti bẹrẹ si ma kọ Nọmba na fun olukuluku lọkunrin ati lobinrin lọmọde ati lagbalagba nitori arun Sanpọnna, Iwọ ti ọmọ rẹ tabi aya rẹ ko ba ti kọ, jọwọ tete mu wọn lọ ki wọn si lọ kọ ti wọn, ọfẹ ni ko si owo nibẹ, awọn alaimọ kan miran a ma sọ wipe lati ọjọ ti awọn ko ti kọ Nọmba arun karun kan ko kọlu awọn rara, ọrọ omugọ gan ni eleyi jẹ, ṣugbọn a fẹ ki ẹ mọ dajudaju pe arun yi si fi oju pamọ si nyin lara, bi o ba pẹ o ni lati jade si yin lara, tabi ẹ si le ko lara ẹniti ẹ jijọ gbe pọ, nipa pe nigbati o ba ti wu kọ, ti iwọ si wa nibẹ ti o jẹ pe arun yi wa lara rẹ iwọ yio ko, ṣugbọn ti o ba ti kọ Nọmba kia kia ni arun yi yio salọ bamubamu. Ṣe ẹnyin na mọ pe epe lafi wo epe san lara were, nitorina ki gbogbo ẹnyin ti ko ba iti kọ Nọmba, jọwọ tete lọ kọ tirẹ lo ni o.

Lakotan ọrọ wa ti ọsẹ yi a wa Oniwe Irohin Imọlẹ fi iwe kekere yi ki gbogbo ẹnyin Olori Oṣelu kakiri ilẹ Afirika ati Malagasy ku abọ si ipade ti ẹ wa ṣe nilẹ yi.

**BRAZIL 111**

FUN IDAGBASOKE TI O GA-A

Awa nta ohun ti o mu ohun ọgbin dara fun (FERTILISER) awọn Agbẹ ati awọn ti o nsin Eran. Ilu wa ni Central Plateau ti Brazil, lẹba ESTATE ti GOIAS ati MASO GRASSO.

Fun idagbasoke Oworẹ nipa Oko ati ohun Ọsin awa wa fun ọ.

A ni ile Iṣẹ wa ni ẹ ba Brazil Olu ilu titun.

Owo ki o lọ nilẹ kiakia £1 8/- fun oṣuwọn hectare kan. Fun ọdun 1961 papa ọdun 1962 jẹ ọdun pataki. Ọna wa fun Mọto ati Ọkọ Ofurufu. Omi pọ, omi Ojo ati ti Odo ti o nṣan.

A ni iwe ẹri fun ọja wa, Ijọba Brazil si fi ọwọ si.

Fun ibere ati itaja kọwe si:-

**Ponciano Blanc Crespo, Agent General for Europe**
AFRICA AND ASIA. EDIFICIO ESPANA
Grupo 5, Planta 21, Despchs 2 - 3 and 4.
Tels 244141 and 2 47 18 18 Madrid, Spain.

A nfe Aṣoju (Agent) ni ilu kankan.

## BAWO LAO SE TUFO YI?

Mo mu ibere yi wa fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ati ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ, Ibere na niyi, nigba kan Iya kan wa to bi ọmọ kunrin kan. Oju Iya ti fọ eti iya yi ti di ọmọ rẹ yi nikan ni o toju iya ti o si fun ni onjẹ. Nigbati o ya ọmọ yi wa ku, Bawo ni a ṣe le sọ fun Iya ọmọ na pe ọmọ rẹ ti ku, nigbati ko gbẹrọ ti oju rẹ si ti fọ, mo nfẹ imọran nipa rẹ.

Emi ni:- O. MUSTAFA, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye No. 7. 27, Maye Street, Yaba

## Dokita Nnamdi Asikiwe nlo se abewo ile Ethiopea



EKO:- A gbọ irohin wipe Ọlọla Gomina agba ilẹ Naijiria Dọkita Nnamdi Asikiwe ti gba iwe ipe lati ọdọ Emperor Haile Salaise lati wa bẹ ilu Abyssinia wo.

Nigbati Asikiwe ba nlọ si ilu na, yio lọ ninu ẹwa Ọla nla rẹ yio si mu diẹ dani ninu awọn Minister rẹ.

Ọjọ na gan ti yio lọ ni a ko ti gbọ, ṣugbọn gẹgẹbi ọpọ ẹnyin enia wa ti mọ, wipe Ọlọla Gomina Agba wayi ko fẹran Irin ajo loju Sanmọ, bayi yio gunlẹ si Kano, Sudan ati Abyssinia.

## Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, biairọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nṣiṣẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ le koko bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWO
16, MOLEYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERIA

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Etekete ti awon Abiku fi nwa Saiye ati bi won se nlo si Orun pada (Apa Kini)

Lati Ọwọ:- ỌLAYIWỌLA AKANDE, NO. 23, OBE STREET, Lagos. Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye No. 186.

Olorun jọwọ maṣe jẹki a bi ọmọ abiku, abiye la o ma bi o, Amin Nigba lailai Ọdẹ kan wa ni ilu yi, ti o jẹ wipe on nikan ni Ogboju Ọdẹ ni ilu na, o ma nlọ si Igbo Ọdẹ fun iwọn ọdun mẹrin tabi ju bẹ lọ, se ẹnyin na mọ pe iru enia bayi ri orişirişi iriri dada.

Ni alẹ ọjọ kan nigbati Ọdẹ yi nlọ latin aginju igbo ni o kan ilu kekere kan, bi o ti fẹ san mọ itosi ile yi, ni o ba ngburo ti awọn kan kun ninu ile, ni o ba rọra dọbalẹ pọ mọ awọn ewe to wa ni bẹ, ile yi si jẹ ile awọn abiku, ibẹ si ni wọn gbe nşe ipade Nigbati o pẹ diẹ ti Ọdẹ yi ti dọbalẹ tan, ni o ngbọ ti Ọga awọn abiku yi dide, ti o nbere lọwọ wọn wipe, on fẹ ki enia mẹta dide ninu nyin, ki wọn ma lọ si aiye, ki wọn lọ wo bo şe ri, ki wọn si tun pada wa, nigbati ikan ma dide, o ni on yio lọ, a mọ ọdọ Ọlorunsọla ni on ma lọ de si, şugbọn ọjọ ti wọn ba bi on, ti o ba di ọjọ kẹjọ ti wọn ma sọ on loruko, ni on yio pada wa si ọdọ nyin pada inu ọga wọn dun, o ni ki o ma jẹ ki ọjọ yẹn yẹ o. Ekeji dide o ni on yio lọ bakanna, gbogbo wọn tun patẹwọ fun, on na tun sọ fun Ọga wọn wipe Mapamilẹkun ni on yio de si o, a mọ ti wọn ba bi on, ti wọn şe ọjọ mẹjọ koja, ti o tasiko ti wọn ma fọn ogunna on jade ninu ile ni on yio pada wa sọdọ rẹ.

## Jaja Washuku gba Asoju Ile Niger Republic lalejo



Ninu Ipade ọjọ mẹta ti awọn Alamojuto eto ilu Ajoji kakiri ilẹ Afirika ati Malagasy fi palẹmọ fun Ipade nla ti awọn Olori Oşelu ilẹ Afirika ati Malagasy bẹrẹ nilu Eko ni ọsẹ tokọja.

Ẹniti a nwo ninu aworan ni Ọgbẹni Jaja Washuku ti işe Alamojuto eto awọn ilẹ Ajoji (Foreign Minister) ti ilẹ Naijiria nigbati o ki M. Madah kabọ, ẹniti o wa şe aşoju fun ilẹ Niger ninu Ipade na.

## Kini o mo nipa ile Afirika

Mo ki gbogbo ẹnyin ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye, ẹ ku ọjọ mẹta, fun anfani gbogbo ẹnyin alakikanju ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ ti ẹ ti nkọ iwe nipa awọn ibere pẹlu idahun ti o ti ma njade loju ewe ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye tẹlẹ ri ni mo şe tun fẹ bere lati maşe bi ti atẹhin wa nitori mo fẹ ki ẹnyin alakikanju ọmọ na ma kọ awọn ibere ati idahun na silẹ ki ẹ si ma ri pe ẹ nka nigbagbogbo, ki o le ran yin lọwọ ninu idanwo ti ẹ o şe ninu ọdun ni fun ile ẹkọ giga tabi idanwo Iwe kẹfa Ijọba (Entrance or G 2. Exam.) Oluwa koni jẹki owo awọn Obi wa jona, ki ẹ ma fi idahun ibere na si ọkan nitori ninu rẹ le lọ jade ni nu idanwo yi lọdun ni.

Kini ohun ti o şẹlẹ nilu Eko lati ojo keji lelogun oşu kini ọdun ni

2. Tani Olotu ilẹ Tanganyika, (b) Ọjọ wo ni ilẹ na gba Ominira?
3. Daruko Alaşẹ ilu Okere fun ilẹ Naijiria (Federal Minister of Foreign Affair
4. Iru Ipade wo ni wọn bẹrẹ nilu Eko tişe Olu ilu Naijiria ninu ọsẹ tokọja lọ yi
5. Darukọ Olori awọn Oşelu ilẹ Niger Repoblic?
6. Ilu wo ni o bẹrẹ Ẹye Ifihan ni eti Okun nilu Eko ni ọsẹ tokọja (trade fair
7. Ọdun wo ni a bi Hamani Diori?
8. Darukọ Ilu marun ti o wa si Ipade awọn Olori Oşelu orilẹ ede Afirika ati Malagasy ti o ti gba Ominira?
9. Tani o şe Aşiwaju awọn Aşoju ilẹ Naijiria ninu Ipade na?
10. Ogbẹni T. O. C. Ojiako tişe Aşoju Naijiria nilu ______ ku ni ọsẹ tokọja.

Wo idahu awọn ibere wọnyi ni oju Ewe keje

## Fa ogbon Ori re yo ninu ibere yi

Ohun idunnu ati imaraya ni yio jẹ fun mi bi Olotu ba le gba mi laye lati kesi awọn ẹlẹgbẹ mi, ki nwọn ba mi şe alaye ọrọ wọnyi, ti o ru mi loju kiakia.

AWỌN IBERE NA NI WỌNYI

Ekini: awọn ọkunrin mẹta kan, orukọ ekini a ma jẹ jẹjẹmimimonlọ, Ekeji a si ma jẹ jẹjẹminimombọ, Ẹkẹta a si ma jẹ jẹjẹminimojoko. Awọn mẹtẹta pade po, nwọn si bẹrẹ si ja tani o yẹ lati da lẹbi ninu awọn mẹtẹta yi. Ekeji: Awọn ọrẹ mẹta kan wa orukọ ekini a ma jẹ Ebinpami, ekeji a si ma jẹ Aramikobalẹ, ẹkẹta a si ma jẹ Temikojọtiwọn. Nigbati awọn mẹta yi lọ si oko, Ebinpami sun işu, Aramikobalẹ nyipo, Temikojọtiwọn fi su jẹ, tani o jẹbi ninu awọn mẹtẹta yi. Ẹkẹta: Nigbakan mo lọ si oko wa, mo fi Iya sile Baba mi ati Iyawo mi ile lawọn mẹtẹta wa, ti mo fi lọ soko, şugbọn nigbati mo ti oko de, nko ba awọn mẹtẹta nile mọ, ogun ti le gbogbo wọn lọ patapata, Tani o wa yẹ ki nwa lọ ninu awọn mẹtẹta? Iyawo mi ni, tabi Iya mi ati Baba mi ni ki nwa lọ ni.

Emi ni Joseph Adelọwọ Kẹhinde
No. 33, Ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye.

# ITAN "KẸTẸKẸTẸ OLORE"

Ni ilu kan Ọgbẹni agbẹ kan mbẹ ti o gbọ gbogbo ede ẹranko ati awọn ẹiyẹ oju ọrun, ni ile rẹ, o ni Kẹtẹkẹtẹ kan ati Malu akọ kan malu yi ni nma mu lọ ro oko lati owurọ titi di alẹ, sugbọn Kẹtẹkẹtẹ ni Ọgbẹni agbẹ yi nma gun ni ọjọ ki ọjọ ti o ba fẹ lọ si ode.

O wa ṣelẹ ni ọjọ kan, o ti rẹ Malu yi fun iṣẹ ti o ṣe, o wa sọ fun Kẹtẹkẹtẹ yi pe aiye itẹrẹ ti dara, nitoripe onjẹ ti o gbadun ni iwọ njẹ ati ibiti iwọ nsun lo mọ finifini, iwọ ko ntilẹ ṣe iṣẹ nigba gbogbo gẹgẹ bi ti emi, afi ẹ kankan ti Oluwa rẹ yio ba fẹ lọ si ode sugbọn emi, ojojumọ ni emi fi nṣiṣẹ gẹgẹ bi lwọfa.

LATI OWỌ

**Latifu Babalola**

AKỌWE AGBA ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Nigbati Kẹtẹkẹtẹ na wo ti anu ti anu, o wa da Malu lohun pe, irọ lo gọ, ti on jẹ ki wọn ma mu ẹ lo lojojumọ, o wa gba ni imọran pe ti o ba di owurọ ti wọn ba wa mu ẹ, lati lọ si oko, ki iwọ se bi ẹniti a r ẹ nṣe to bẹ gẹ depo pe, bi wọn ba ko igi bo ẹ, ki o ma dide ki o se sugẹsugẹ, wọn yio fi ọ silẹ, iwọ yio si ri aye lati fi simi.

Wọn ko mọ pe Olowo wọn ngbọ gbogbo ohun ti wọn nsọ, nigbati ọmọ ọdọ Olowo na de ni owurọ ọjọ keji lati mu Malu lọ si oko, Malu na nṣe bi ẹniti ara rẹ ko da, depo pe ki o tilẹ fi ẹnu kan onjẹ ti wọn gbe fun lati ana nigbati ọmọ ọdọ Olowo yi se akiyesi pe o ni lati jẹ wipe aisan wa lara Malu yi ni, o dide lati lọ sọ fun Olowo wọn pe ara Malu ko da o, Ọgbẹni Olowo yi ni ko buru, ki o lọ tu Kẹtẹkẹtẹ yẹn lọ siṣẹ oko loni, nigbati wọn mu Kẹtẹkẹtẹ yi de oko, wọn lo titi o fi ko arẹ to bẹ gẹ ti o fi ko abamọ, ti o si sọ pe on ni on fi omugọ pa ara on to yi, nigbati wọn de ile, Malu ki pe ki o ku bọ, o ṣe imọran ti o fun on, Kẹtẹkẹtẹ yi ko da lohun, sugbọn o nwa ọgbọn ti yio tun fi ti Malu si iṣẹ rẹ pada.

Ni igbati Kẹtẹkẹtẹ yi nro gbogbo iya ti on jẹ loko, o bu si ẹkun, ni Malu yi ba bi lere pe iwọ ọrẹ mi o ṣe ti o fi nsunkun? Kẹtẹkẹtẹ si da lohun pe, o ṣe iwọ ọrẹ mi, ọrọ ti mo gbọ nipa rẹ nigbati Oluwa nba ọmọ ọdọ rẹ sọ nipa rẹ lo npa mi lẹkun, malu na si bi wipe, bawo, o si da lohun pe, hun, on gbọ nigbati Olowo wa mba ọmọ iṣẹ rẹ sọrọ pe bi o ba ti di owurọ ọla ti malu ko ba dide lati lọ si oko pipa ni ki o pa, ki o si lọ ta ẹran ara rẹ ni ọja, eyi ni nkan ti o npa mi ni ẹkun, malu si da lohun pe o ṣe, Olodumare yio tun tirẹ ṣe, bi o ba ti di owurọ ni emi yio ti ma fo soke pe, ara on ti le.

Ni owurọ ọjọ keji ti ọmọ iṣẹ Olowo yi ti yọ lati fun wọn ni onjẹ ni malu ti nlanu ti o si nfo soke lati le fi han ọmọ iṣẹ Olowo yi ki wọn ma le mu lọ pa, o si jẹ gbogbo onjẹ ti wọn gbe fun kiakia.

Bayi ni malu ṣe bẹrẹ iṣẹ rẹ ti Kẹtẹkẹtẹ fi pada si ipo idẹra rẹ. Eleyi kọ wa pe bi a ba ni ọgbọn ki a fi si ọkan ara wa, enia ko lẹ du ori olori ki awodi si gbe tirẹ lọ. Iwaju ni gbogbo wa yio ma lọ o, o di gba kan na.

## Owo de si agbegbe Ilorin lodun ni

OFFA:— A gbọ irohin po ni itosi odo kan ti awọn Oyinbo Reluwe ṣe silu Ọffa nibiti oko Reluwe ati awọn Oṣiṣẹ rẹ yio ti ma ri omi mu ti wọn ope ni odo Afẹlẹlẹ.

Ibeere dide si wipe eto ti a fi gbọ wipe epo moto ati epo Korosini se yo jade lati inu ile laije wipe enikan lo wa a jade. Awọn Oyinbo ti o nwa Karosini ati epo moto ti won npe ni Shell Bipi je bulu ala ere lodun to nbo owo epo moto. Ni odun tokoja, o le ni oke mesa Korodumo epo moto ti awon wa jade ninu ile lojo kan.

A gbo lenu awon Oyinbo Oniwowo Epo wipe, bi ayo ba fi to odun 1965, awon o ma wa Korodumo epo moto pupo to oke marun lojo kan. A ni aniyan wipe nigbati awon ba bere si wa epo ti Offa pelu, ko tile ni pe to odun 1965 ki awon to bere si gbon epo moto bi iwon oke marun Korodumu lojojumo.

## Ipinle Ila Orun ranse fun ero ti o nse Panu onisimenti



Ijọba Ipinlẹ Ila Orun nfi ọwọ si iwe adọta Ọkẹ Pọnun lati ra ẹrọ ti o nṣe Panu Onisimẹnti lọdọ Gẹsi. Orukọ awọn ti a nwo ninu aworan yi ni Dr. M. I. Opara, Oloye F. U. Nwodo A. Nere, R. M. Bateman. Bi ẹrọ na ba de yio gba to iwọn ọdunrun enia lati ṣiṣẹ ẹrọ na.

## Ara Saro ati ara Naijiria nki ara won



Awọn meji ti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni J. C. O. Crowther ọmọ Bishop Crowther ti o bi si ilu Saro ati Alhaji Isa Kaita Naijiria, awọn mejeji pade ara wọn ni Igbimọ gbogbo Agbaiye nilu Oyinbo, wọn si mba ara wọn sọrọ irẹpọ.

# Imototo Ninu Ile re ( Apa Kini )

Lati Ọwọ:- ONIṢEGUN IROHIN IMỌLẸ.

Kinto ma ba ọrọ mi ọsẹ yi lọ mo ni lati dupẹ lọwọ gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ pe, ẹ ku suru ti ẹ fi nka ọrọ mi na, Oluwa yio ma ran yin lọwọ, ọpọlọ ti ẹ nfi ka ọrọ na koni daru mọ yin la gbari, Ire Owo, Ire Ọmọ fun gbogbo wa o Amin.

Bi a tise ni lati tọju Ile wa jẹ pataki (Important) ọrọ mi ọsẹ yi Obinrin Ile ti o ba dara ni lati kọ bi a tise ni lati ma tọju Ile Ọna ti a o ma gba tọju awọn Ọmọ Ọwọ wa ti wọn yio fi wa ni alafia laiko si arun lara wọn, Imọtoto yi ni ole mu awọn ọmọ ọwọ bori awọn ajakalẹ arun ode oni ti o nma owa lara awọn idọti gẹgẹbi Aṣọ didọti tabi Ile ati Ibusun ti a a kọ moju to.

ỌNA TI A LE FI MA GBA ILE WA

Nigbati a ba fẹ gba ilẹ ile wa a ni lati ranti awọn ohun meji wọnyi:- Ekini:- Kodara pe ki a gba ilẹ nibikan ki a tun wa lọ gbe si bomiran ninu ile, a ni lati gbe Iẹsẹkanna lọ junu si ọna jinjin (Akitan) ni Ekeji:- Ni wipe ibiti a ni lati ma da ilẹ si ni lati jẹ ibi ti a mọ pe akitan ni, ti o si jina si ibiti Enia ngbe.

OHUN TI A NI LATI MA LO LATI FI MA NU IDỌTI

Ni Orişirişi Ọna:- Bi a ba fẹ gbalẹ ti o ndan gẹgẹbi Carpet ani lati lo igbalẹ ti o dara pẹlu omi ati akisa ti o ba si jẹ Simẹti ani lati lo ọwọ Oyinbo ti o bẹ. Bi o ba jẹ pe Apoti tabi Kọbọdu tabi orişişi ohun ti o dan ti awọn Gbẹna-Gbẹna ṣe ni, ani lati lo aşọ fẹlẹfẹlẹ lati fi nu ti o ba jẹ apoti eyiti a ko fi epo pa lara ni a le lo Burọsi lati nu.

BI A T.SE NGBA ILẸ INU ILE

Bi a ba fe gba ilẹ inu ile ani lati ti Ilẹkun ati Ferese ki a to bẹrẹsi ngbalẹ nitori bi a ba şi wọn silẹ atẹgun yio gbe ilẹ ti a fẹ gba kakiri gbogbo ile ti a ko si ni mọ nigbati o ba pọ diẹ yio di Idọti, Arun kan ni eleyi yio si tun fa fun enia ti o ba wọ aşọ na kodara ki a ma jẹ ki atẹgun ma nfẹ ilẹ ti ngba lọwọ lọwọ nitori ti o bati gba yọn, nseni ẹniti o ngba y i o mi eruku ile na nitori o yọ ki a ma şọra wa ti a ba ngba Ilẹ Ile wa.

---

## EYI TO KU NINU ITAN IGBESI AIYE MI NINU IGBO IRONUPIWADA (APA 3) TI ỌSẸ TO KỌJA

mo fẹ sọ itan kekere kan fun ẹ iwọ ọmọ enia Ẹniti orukọ rẹ njẹ "APẸKUNJOYE" Itan mi na ni eyi. Nigbaatijọ ri awa Iwin ama di Enia a si ma nwa şi I l u lati wa şọ iwa awọn ọmọ araiye, Odi ọjọ kan mo wa gẹgẹ bi Ọkurin mo si ri ile nla kan ti wọn nkọ mo duro mo nwo ile yi ati awọn to nşişẹ lori ile yi ibiti mo ti duro si ni Oyinbo wọn de ba mi ni iduro, bi o si ti bọlẹ ninu mọto, o lọ wo Işọ awọn oşişẹ rẹ.

Sugbọn alai koni suru Oyinbo yi ko jẹ ki owo işẹ na pẹlu suru, bi oti jau jau ija ni ogbe ko awọn oşişẹ rẹ loju, sugbọn ọga awọn onişẹ yi ti kọ suru dada gbogbo bi Oyinbo yi ti nwi koda lohun nigbati ori ọkan rẹ balẹ ope osi fi suru laye Oyinbo dada nigba yi ni Oyinbo na wa fi suru wo ti osi ripe işẹ wọn na dara gan, Ipari itan mi na niyi iwọ ọmọ enia odigba o.

Baba mi na si dalohun dada osi pada wa le ni ọsan ọjọ keji ni bayi mo ma duro lọsẹ yi o.

---

AKIYESI FUN ENITI O FẸ RA TABI TA ILE TABI ILẸ NI IBI GBOGBO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ra tabi tita tabi fifi ile ya tabi lati haya gbogbo ile to dara ti o si laye tabi ile işẹ tabi ilẹ ti ko pọju adọta ẹsẹ ni fifẹ ati ọgọrun ẹsẹ ni gigun, nihin tabi lọhun ati nibi gbogbo, bi Eko, Ebute mẹtta, Apapa Yaba Suru Lere, New Lagos, ati paapa ni Idi Oro, Mushin Isọlọ Road ati Ikẹja tabi nibikiki, Wa ri Ọgbẹni:-

**J. B. Crownson Odujobi & Sons**

1st floor 16, BAMGBOṢE STREET LAGOS

Tabi ki o pe wa lori ọrọ Isọrọ No 24318.

DIRECT ALL YOUR PRINTING JOBS TO:—

**MODUPE PRINTING PRESS**

16, BAMGBOSE STREET LAGOS

---

## Obinrin nko bi a ti se nfi Esin Jagun



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Omiden Catherine Evans ni Obinrin ti o Nigboya lati koko lọ niwaju Ijọba wipe on fẹ ko Işẹ bi a ti şe nfi Ẹşin J u g u n , o si jẹ ọmọ Ọdun Mejidilogun.

---

## Iwo ha Nfe Igbega bi?

Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, ti ko le mọ ile Işẹ wa ni Mushin, ni a şe ko awọn apakan ninu ọja wa, wa si Nọmba 16, Bamgbose Street, Lagos, ẹnikẹni ti o ba fẹ ra ọja wa ni Eko ki o ma lọ sibẹ.

TURARI AJẸBIDAN AGBABIETU

Turari yi ko ni ẹgbẹ akose fun awọn ajẹ ni, ti o ba loo iwọ ko ni mọ a i t a ọja. Adura rẹ yio si ma a gba Awọn enia buruku aiye kolẹ ni lagbara lori rẹ onşẹẹ to igba ọna (200 ways) fun igbega ọmọ enia ni le A i y e. (Pangolo 10/6d)

MANAGER (J. O. SHOYINKA.) c/o IROHIN IMỌLẸ
16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.

# Igbesi Aiye Mi Ninu Igbo Ironupiwada (Apa 4)

Lati Owo:- TAJUDEEN A. ADEBOUN.
No 40, OMO EGBE IMOLE AIYE

Enyin Olukawe mi mo rope e o fe lati ma gbadun mi siwaju ensi na ti a wa lati ma fun yin ni itan aladun na. Gegebi e ti gbo Iruumo Oruko mejeji yi, e o le gbo ohun ti o sele si Baba mi ati Iwin yi. Lehin ti awon mejeji ti tonmo Oruko ara won fun ra won tan ni nwon si no mo ara won ti won ki ara nwon daradara ni, Baba mi wi fun pe on nlo sugbon nigbati baba mi ma fi ma kuro lodo Iwin yi Omi fere ma bo loju re sugbon ofi Igberya pe iwin na, o si bi lere ohun ti yio fi ta on lore Iwin na ki owo bo apo re osi mu Atare Odindi kan ati Iye kan jade o si mu fun baba mi, Baba mi gba lowo Iwin na o si dape lowo re owi fun pe jowo, ere mi bawo ni nio se ma lo? Iwin na dahun pe bi ogun ba de bi Baba mi ba je eyo atare kan ki o mu iye na dani yi o di Eiyekeye ti o ba fe de, Baba mi si ju si apo ode re odupe lowo Onirurukoinikahamolaiye. Ati fi Iwio na sile pelu alafia ati Ayo, Atilo Enyin Olukawe mi mo fe ki e mo pe ninu Igbo yi ni ile mo ba wa ti o on tuo ti eja wa su, nigbati ebi nga wa a sun Eran Odugbo na a si je. Nigbati ati ma kuro lodo Iwin yi ile tisu kikura ti akuro lodo re Igbo O d e si ni alo ati nwo Igbo kin bi ati ti orjo kiri ni a dede ri gbogbo Igbo na to daru ti gbogbo Eranko si nsa kakiri ti awon Eiye ti oti sun tele ti efo kiri, Nigbati ari ami yi Baba mi si so fun mi pe ki ama mura nitori pe ohun abami kan ti onle awon Eranko yi bo. Be si ni ari awon Eku ti rsare si Otun ati Osi, Gbogbo Igbo npa riwo o.

Nigbati awoye tan a ko ri Idawo duro kan Igbona tubo npariwo ni ni emi ati Baba mi si gun igi lo lati fi ara pamo lehe Ewe Igi na o pe die ti ati gun Igi na ni ari ohun to ninu Igbo ne pariwo Iwin ni sugbon Iya lenu ibe ni pe iwin yi ko ga ju Ese Bata merin lo ati pe iru won yi ni ole ma da Igbo na ru to be yen, nitori eyi Baba mi sokale lati ori I g i na osi fi ibinu loba Iwin yi o wi fun pe kini de ti iwo nle awon Eranko wen yi? Iwin yi da Baba mi lohun dadaa o si wipe Jo-o, Olegbeni jeki emu lo nitori pe E m i na nsa lo ni, ati pe ohun to nda Igboru na mbo lehin.

Nigbati owi bayi tan Baba mi bere Oruko re osi dahun pe KANISURU ni Oruko on Baba mi osi ki osi mbo nitire Bayi ni atubo ngburo ariwo na gan, Teletele oko beru rara sugbon ni asiko ti a nwi yi mo ti fe su si ara mo si ti da Idio si ori igi na.

**Nitori** pe gbogbo Igi lo wa nmi si osi, ati otun kosi dawo duro atiwo rara. Baba mi si sare gun igi pada nitoripe ero okan wa ni pe ohun to nbo ni lati ni Eru lo jeki awon Eranko ati Eiye ma sa fun.

Nitori eyi ori oke igi na ni awa wa fun igba pipe ti a ko si soro ti a ko huko gbekan a ko mi fin larin emi ati Baba mi, mo si wo sin bi oba panu, nigbati o se a ri ohun to nda Igbo ru, Esu ni pelu awon Iranse re awon iranse re yi po gbogbo won lo si ru awo ebo kankan ti won lo gbe ni Ikorita, won siwaju Esu Oga won si tele won. Sugbon o de odo wa o dan mi wo pe ki nyin Baba mi ni ibon, sugbon mo wi fun pe pada lehin mi iwo Satani. Nigbayi ni o ulo nitire bayi ni emi ati Baba pada sile lojo na, a ko si ri iyonu miran ju eleyi lo sugbon a ri eran die pa.

## Awon Alejo ti o wa be Ile Naijiria wo



Enin a nwo ti o njade kuro ninu Moto yi ni Monsieur-Freitas Paulin tiis A l a m o j u t o Eto awon Ile Ajoji ni I l e Togo ti o wa se Asoju fun Ilu re ninu Ipade gbogbo awon Alamojuto Eto ile Ajoji kakiri Ile Afirika ati Malagasy se nile Naijira.

BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE
TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun itoju tabi fifo Apo Ile ito Kidney-Bladder fun Okunrin ati Obinrin bi awon amodi wonyi ba nyo o lenu Ehin didun eri ile tabi ito-jijo enia, ito ririn, rukuruku Pipon tabi ririn, Iakuregbe, Ibara di wiwo, orunkun, owo, ese Ejika wiwu tabi riro.

Ara s'san, titobiju, aiko le ... ara konkon tabi kiakia, diduji ... nigbakugbe, ati orsirisi awon ... tabi amodi ba wonyi ni egbogi ... bidan yi yio wo san lara re ni kia kia ti alafia yio si de si o. Meji re ko si ni Ilu Naijiria nitorina ... ki awon eleru tabi awon Oni ... robi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun o, mase gba a rara o! Owo re je Sile Mefa abo 6/6d owo oko sile meji abo (2/ 6d)

Bere Egbogi yi ni Sobu awon Saro ti won npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI AWON SOBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA

## Tani o goju ninu awon ore meta yi

Lati Ọwọ:- Surakatu Ajisafẹ Ọttun

Inu mi yio dun ti Olotu ba le gba mi laye ninu iwe Irohin Imọlẹ lati fi itan mi kekere yi siwaju awọn ọjọ gbọn Onkawe Irohin Imọlẹ lati la ẹniti o ba gọ julọ ninu awọn ọrẹ mẹta wọnyi y e m i. Itan na lọ bayi: Awọn emugọ mẹta kan wa, wọn si jẹ kori kosun, nigbati o ṣe awọn mẹtẹta da amọran wipe o yẹ ki awọn sisọ lọ si ẹhin odi (Idalọ) nijọ kan wọn mura, wọn nlọ, ibiti wọn ti nlọ ni won ri ọwọ awọn ọmọ ogun (Soldiers) ti o mbọ lẹhin wọn. Omugọ kini lo kọ damọran wipe ọ yẹ ki awọn sapa mọ, ibiti o ti wi eleyi na gan lojukanna ko pa ẹsẹ da mọ latin titi lo ba kunlẹ sarin titi, ekeji sa si ẹgbẹ titi ṣugbọn ọkẹta gun igi lọ. Bi awọn ọmọ ogun yi ti de ọdọ wọn eyiti o kọ damọran pe ki nwọn sa pamọ ni wọn kọ kan ti wọn si kẹ pa, ni wọn ba tun taju kan ti wọn si ri ti ẹgbẹ titi na, wọn si tun pa on na, ṣugbọn wọn ko ri ẹkẹta wọn, ti o gun igi lọ, ibiti awọn ọmọ ogun na ti fẹ yi si ibiti ohun ẹnikẹni ko ti le gbe to wọn mọ, lo ba ke si wọn pada pe, hun si ọ yin lẹmeje, njẹ bi awa tiṣe ngbe ẹsẹ nigba ogun kiraji ti wọn fi npe wa ni ọmọ ogun ni ẹyin ngbe ẹsẹ yẹn? Wọn ni ha! a ṣe ẹtun ku nibẹun, ni wọn ba pada wa pa on na.

Inu mi yio dun ti awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ba le la ẹniti o gọ julọ ninu awọn Omugọ mẹtẹta wọnyi yemi.

## Obinrin ti oko re ko sile, tun fe pada sodo oko na

Lati Ọwọ:- Amọsa Ọlọruntẹlẹ

MO NFẸ IMỌRAN LATI ỌDỌ ẸNYIN ỌKAWE IROHIN IMỌLẸ

Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye ati bi ẹ ba le fun mi ni amọran ọrọ kekere yi. Ọrọ lori Iyawo mi ti orukọ rẹ njẹ Muniratu Amọkẹ ara Ilọrin ti mo kọ silẹ, to tun lepa mi kakiri. Ohun ti Iyawo mi na ma nṣe ati ti o ma nhu ni iwa ni wọnyi:- O nṣe ohun ti ko tọ, o njade laiko sọ fun mi, o ngbe ọkunrin miran wa sile bi mo ba jade o si tun ma nlọ mọ mi ni ita bi ede aiyede ba wa ni arin wa, bi mo ba sọ fun pe ki o ma ṣe nkan, nkan na lo ma nṣe, ko ni iteriba fun mi ati awọn Obi mi pẹlu awọn alabagbe wa.

Njẹ o ni ẹtọ lati fẹ iru Iyawo bẹ pada, lẹhin ti mo ti kọ silẹ, ti o si ti jade ninu ile mi?

## Olopa obinrin ilu Saro kan gba okun



Olori Ọlọpa Obinrin k a n ti o jẹ Oyinbo ti orukọ rẹ njẹ Conoch fun Olori Ọlọpa obinrin enia Dudu kan ti o njẹ Winifred Barker ni okun, okun yi ti o ba lo ni yio fi ga soke ju awọn ẹlẹgbẹ rẹ yoku lọ.

## Kini O mo Nipa Ile Afirika?

EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE TO WA NI OJU EWE KẸTA

(1) Ipade awọn Alamojuto Eto Ilu Ajoji Kakiri Ilẹ Afirika ( Foreign Minister of Africa & Malagasy ) ati Malagasy bẹrẹ nilu Eko. ọpọlọpọ alejo de silẹ Naijiria fun Ipade awọn Olori Oṣelu Ilẹ Afirika

(2) Ọgbẹni Julius NYERERE, won gba Ominira ni Ọjọ Kẹsan Oṣu Kejila Ọdun 1961.

(3) Ọgbẹni Jaja Wachuku. (4) Ipade awọn Olori oṣelu Ilẹ Afirika ati Malagasy (5) Ọgbẹni Hamani Diori

(6) Ilu Canada. (7) Ọdun 1916.

(8) Niger, Mali, Togo, Senegal, Cameroon Republic.

(9) Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa.

(10) Asoju Naijiria nilu Western Germany.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O SEṢE DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ti irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ de ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de wọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹE-emi (breath) inu ko ba gunlẹ dara ara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJẸ" fun wọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja ọgbọn ọ d u n lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daja pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara njọ Otun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hgba yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn n kugba "Arẹ" nigbakubga yio salọ patapata

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji;**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

FEDERATION OF NIGERIA THIRD DEVELOPMENT LOAN

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966 - to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986 - to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

*W. A. TIBBLES.*
*General Manager.*

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.

BERE OJULOWO EGBOGI WỌNYI:-

**"Congreve Female Remedy"**

EGbogbonse fun Itọju tabi Ajo Obinrin fun Inu riru n ba di riro tabi gige nigbakugba, ati orişirişi arun tab amọdi ti o ma nyọ Obinrin lẹnu ni Inu nigbakugba-

**"Collomack"**

Egbogi awọn Jamani ti o dara julọ fun Itanpara, awọ ẸSẸ lile, Igbado ẹsẹ ti ki jọki enia le wọ bata (Corn-cure) ati orişirişi arun Ẹsẹ miran pẹlu ni

**"Mackotal"**

Atamatase Egbogi awọn Jamani fun orişirişi amodi "ETI" riro tabi didun fun ọmọde ati agbalagba bi o ti wun ki ọjọ rẹ ti pẹ to yio şe iwosan rẹ ni kiakia.

**"Medupríval"**

Ojulowo egbogi awọn ara ilu Tatanbulu fun iwosan ni kiakia gbogbo amodi tabi OTUTU Agbari, Igba aiya Ọna-ọfun, Imu tutu tabi ti o ma nsọmi bi ikun nigbakugba, Kẹlẹbẹ ọna ọfun tabi agbari hiha, amurun ati orişirişi amodi miran gbogbo ti ibẹrẹ rẹ jẹ otutu. Bere ti Ọmode tabi ti agbalagba wọn yatọ nipa agbara wọn ni o

Bere ni Şọbu:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WA KEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OŞHOGBO.

HOUSE & LANDED PROPERTIES

If you want to buy or sell lease or rent new and decent buildin with spacious rooms and modern amenits rooms offices also landed properties 50x100 etc here and there Lagos Ebute Metta Apapa Suru lere New Lagos especiolly at Idioro Odi olowo Mushin Isolo road Ikeja e t c CONULT:-

J B CROWNSON ODUJỌBI, Top Floor, 16, BAMBOSE ST. Lagos or Phone 24318.

## Omo Egbe Alakuko kan wole ni Oyingbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni M. O. Mọtayọ, ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C.) ti o wọle ninu Ibo Igbimọ ibilẹ Ilu Eko, (Lagos Town Council) fun agbegbe Oyingbo F. 5 ward.

Iye awọn ti o gbe wọlẹ jẹ 804, ohun ti o jẹki ibo na ya kiakia bẹ ni pe ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti o njẹ Ọgbẹni B. Ilesanmi lo towọ bọ iwe pe on ko şe ẹgbẹ Alakukọ mọ. Iye awọn ti o dibo fun Ọgbẹni Ọlatunde Ipese ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ jẹ 603.

Apapọrọ ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ninu Igbimọ ilu Eko jẹ mejilelogu; ti ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ jẹ ogun.

## Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ Ẹku afojuba egbogi pataki ti a şe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Onişegun (Specialist) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ arun wọnyi:-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o ti şọpọ ni isisinyi papa ni arun awọn Omode ati Agbalagba.

ORI FIFỌ TULU LUKULULU, OTUTU IGBA AIYA ARA RIRO ati OTUTU ORẸREN pẹlu AKOKORO.

Jọwọ danwo ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko to afojuba. Bere iwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin: O daju hanwun. Ẹ o ri işẹ rẹ lẹhin işẹju mẹdogun ti ẹ lo Bere lọwọ Onişegun adugbo rẹ.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
Bishop Sreet Phone; 23745
LAGOS

Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Oloto E. A. Adeniji 24, Oliyide Street, Odo Abọrẹ MUSHIN.